# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**OṢÙ KINNI, ỌDÚN 2025**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**&**

**Ìtúsìlẹ̀ Àwọn Àkọ́bí**

**OṢÙ KINNÍ, ỌDÚN 2025**

**1. Ọkàn mi yin Ọba ọ̀run,**
Mú ọrẹ wá sọ́dọ̀ Rẹ,
'Wọ ta wòsàn, t'a dáríjì
Tal'ába ha yìn bí Rẹ?
Yín Olúwa, Yín Olúwa,
Yín Ọba àìnípẹ̀kun.

2. Yín fún ànú t'ó ti fi hàn
F'áwọn Bàbá 'nú pọnjú
Yín Ì Ọ̀kan ná nì tití
Ó lọ́ra láti bínú
Yín Olúwa, Yín Olúwa,
Ológo n'nú òtítọ́.

3. Bí Bàbá ni Ó ntọ́jú wa
Ó sì mọ àìlera wa;
Jẹ́jẹ́ l'ó ngbé wa lápá Rẹ̀
Ó gbà wá lọ́wọ́ ọ̀tá
Yín Olúwa, Yín Olúwa
Ànú Rẹ̀, yí ayé ká.

4. Ángẹ́l, ẹ jùmọ̀ bá wa bọ
Ẹ̀yin nri lójúkojú
Òrùn, Oṣùpá, ẹ wólẹ̀
Àti gbogbo àgbáyé
Ẹ bá wa yìn, Ẹ bá wa yìn
Ọlọ́run Olótìtọ́

**1. Ọlọ́run t'ọdún t'ó kọjá**
Ìrèt'èyí tí mbọ;
Ib'isádi wà ní iji
À t'ilé wà láíláí.

2. L'ábẹ́ òjìjì ìtẹ́ Rẹ
L'áwọn èyàn Rẹ ngbé
Tító l'ápá Rẹ̀ nìkanṣo
Àbò wa sì dájú.

3. K'áwọn òkè k'ó tó dúró
Tàbí k'a tó d'áíyé
Láíláí Ìwọ ni Ọlọ́run
Bákanná, l'áìlópin!

4. Ẹgbẹ̀rún ọ̀dun l'ójú Rẹ
Bí alẹ́ kan l'ó rí
B'íṣọ̀ kan, l'áfẹ̀mọ́júmọ́
Kí òrùn k'ó tó là

5. Ọ̀jọ̀ wa bí òdò ṣíṣán,
Ọ̀pọ̀ l'ó sì ngbé lọ;
Wọ́n nlọ, wọ́n di ẹni 'gbàgbé
Bí àlá tí a nrọ.

6. Ọlọ́run t'ọdún t'ó kọjá
Ìrèt'èyí tí mbọ̀
Má ṣ'àbò wá 'gbà 'yọnu dé
À t'ìlé wá láíláí.

## ỌRỌ̀ AGBÁRA

1. Gbogbo ọ̀rọ̀ òdì tí wọ́n sọ lòdì sí ayé mi l'ọ́dún yìí yóò padà sọ́dọ̀ àwọn tó rán an lónìí, ní orúkọ Jésù.
2. Gbogbo irètí sátánì fún ayé mi l'ọ́dún yìí, mo pàṣẹ kí o di asán àti òfo lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Lónìí, èmi yóò gba agbára tí àwọn ọ̀tá mi kòlè takò l'ọ́dún yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Àwọn ohun tuntun tí yóò gbé ayànmọ́ mi lọ sí ìpele t'ókàn yóò gbé ayé mi wọ̀ lónìí, ní orúkọ Jésù.
5. Lónìí, Olúwa yóò fún mi ní ifòròróyàn láti dìde gaju gbòngbò mi lọ l'ọ́dún yìí, ní orúkọ Jésù.
6. Lónìí, nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ògo ayé mi yóò farahàn, gbogbo òkè ìpọ́njú mi yóò pòórá, ní orúkọ Jésù.
7. Lónìí, Olúwa yóò gbọ́ àwọn àdúrà mi dé ìpele dídójúti àwọn ọ̀tá mi, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

**ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Mo múso gbogbo pámpẹ́ ẹ̀mí òkùnkùn tí wọ́n dojú rẹ̀ kọ mí l'ọ́dún yìí, ní orúkọ Jésù.
4. L'ọ́dún yìí, Jèhófà yóò dìde nínú ìbínú Rẹ̀, y'Ó sì jà fún mi, ní orúkọ Jésù.
5. Èmi kòní wọ aṣọ ibànújẹ́ l'ọ́dún yìí, ní orúkọ Jésù.

6. Agbárakágbára tí wọ́n yàn láti pa mí l'ọ́dún yìí yóò pa ara rẹ̀, yóò sì kú, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo pẹpẹ búburú tí wọ́n gbé dìde lòdì sí mi l'ọ́dún yìí yóò wólulẹ̀, ní orúkọ Jésù.

## <u>ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ</u>

**1 Kọ́ríntì 15:57:** Ṣùgbọ́n ọpẹ́ ni fún Ọlọ́run ẹnití Ó fi ìṣẹ́gun fún wa nípa Olúwa wa Jésù Krístì.

**Ìfihàn 12:11** Nwọ́n sì ṣẹ́gun rẹ̀ nítorí ẹ̀jẹ̀ Ọ̀dọ́-Àgùntàn ná, àti nítorí ọ̀rọ̀ ẹ̀rí wọn, nwọn kò sì fẹ́ràn ẹ̀mí wọn àní títí dé ikú.

**Hébérù 4:12** Nítorí ọ̀rọ̀ Ọlọ́run yè, ó sì lí agbára, ó sì mú ju idàk'dà olójú méjì lọ, ó sì n gúnnni àní títí dé pípín ọkàn àti omi níyà, àti òríkè àti ọ̀rá inú egungun, òn sì ni olùmọ̀ èrò inú àti ète ọkàn

**Fílíppì 4:13** Èmí lè ṣe ohun gbogbo nínú Krístì ẹnití nfi agbára fún mi.

**2 Kọ́ríntì 10:4:** (Nítorí ohun ìjà wa kì íṣe ti ara, ṣùgbọ́n ó lí agbára nínú Ọlọ́run láti wó ibi gíga palẹ̀;)

**Kólóssè 2:15:** Ó sì ti já àwọn ìjọba àti agbára kúrò lí ara rẹ, ó sì ti dójútì wọ́n ní gbàngbà, ó nyọ ayọ̀ ìṣẹ́gun lórí wọn nínú rẹ̀.

**Lúkù 10:19:** Kíyèsi i, èmi fún nyín lí àṣẹ láti tẹ ejò àti àkékè mọ́lẹ̀, àti lórí gbogbo agbára ọ̀tá: kò sì sí ohùnkan bí ó ti wù kí ó ṣe, tí yóò pa-nyín-lára.

**Rómù 8:31:** Njẹ́ kíli àwa ó ha wí sí nkan wọ̀nyí? Bí Ọlọ́run bá wà fún wa, tani yóò kọ ojú ìjà sí wa?

**Rómù 8:37:** Ṣùgbọ́n nínú gbogbo nkan wọ̀nyí, àwa ju ẹnití ó ṣẹ́gun lọ nípa ẹnití ó fẹ́ wa.

**Rómù 8:39:** Tàbí òkè, tàbí ọ̀gbun, tàbí ẹ̀dá míràn kan ni yóò le yà wá kúrò nínú ìfẹ́ Ọlọ́run, tí ó wà nínú Krístì Jésù Olúwa wa.

## KÓKÓ ÀDÚRÀ FÚN ÌTÚSÍLẸ̀ ÀWỌN ÀKỌ́BÍ

**Ìjẹ́wọ́:** Mo **jẹ́** àkọ́bí. Èmi ni ìpilẹ̀ṣẹ̀ ipá ìdílé mi. Mo jẹ́ títayọ ọlá, àti títayọ agbára. Èmi kòní jẹ́ ajigbesè nínú ayé yìí. Èmi yóò fìdìmúlẹ̀ bí àpáta. Èmi yóò tayọ, kòsí ẹnití yóò kó àdàlù bá mi. Èmi kòní kú ikú oró. Èmi kòní jẹ́ ọlọ́jọ́ kúkurú, bẹ́nì èmi kòní di àgbà tíkò ní mú àwọn ọdún rẹ̀ ṣẹ. Èmi yóò ní ipa Sámsónì, àmọ́, kì íṣe àìkíyèsára rẹ̀. Èmi yóò ní ọgbọ́n Sólómọ́nì, kì íṣe ìwà àgbèrè rẹ̀. Èmi yóò ní ìwà-mímọ́ Jóbù, kì íṣe àwọn àjálù rẹ̀. Èmi yóò gba ẹnubodè àwọn ọ̀tá mi. Èmi kòní jẹ́ èrò ìrora tàbí òṣì. Àwọn ọ̀tá kòní borí mi. Olúwa yóò fi òróró ìdùnnú yàn mí jú àwọn ẹlẹ́gbẹ́ mi lọ. Iná ọ̀tá kòní jó mi. Mo fi ara mi jìn lónìí sí Ọlọ́run Ábráhámù, Ísáákì àti Jákọ́bù, àti Bàbá Jésù Krístì Olúwa wa. Àmín.

1. Gbogbo ègún òbí tó n rẹ ayé mi sílẹ̀, fọ́ nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
2. Gbogbo gbólóhùn látọ́dọ̀ bàbá àti ìyá, tí wọ́n sọ lòdì sí ayé mi, kú, ní orúkọ Jésù.
3. Mo pàṣẹ wí pé àlùmọ́nì àkọ́bí mi kòní wà nínú àhámọ́, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo iṣẹ́ sàtánì láti gbé àkọ́bí mi sin, túká, ní orúkọ Jésù.
5. Mo kọ ẹ̀mí ìrù; mo gba ipò orí, ní orúkọ Jésù.
6. Nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, mo fọ́ gbogbo ètò àjẹ́ tí wọ́n yàn láti ṣe pàṣípàrọ̀, àti láti kó àdàlù bá ìràwọ̀ mi, ní orúkọ Jésù.

7. Gbogbo ègún àti ìpọ́njú tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí àkọ́bí nínú ìdílé bàbá mi, kú, ní orúkọ Jésù.
8. Gbogbo ìfinijìn tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí mi gẹ́gẹ́ bí àkọ́bí, gba ìparun, ní orúkọ Jésù.
9. Mo ṣe ìparun fún agbára Hẹ́rọ́dù ìyówù tí wọ́n yàn láti daàmú ayànmọ́ àkọ́bí mi, ní orúkọ Jésù.
10. Májẹ̀mú ìyówù tí àwọn bàbá nlá mi tilè ṣe lórí ayé mi gẹ́gẹ́ bí àkọ́bí, di fífọ́, ní orúkọ Jésù.
11. Gbogbo ipá àjẹ́ tí wọ́n yàn lòdì sí ìrawọ mi, kú, ní orúkọ Jésù.
12. Agbára ìyówù tó n ṣi iràwọ̀ mi darí lọ sí ibòmíràn, kú, ní orúkọ Jésù.
13. Gbogbo ọfà ọlánrẹ̀yìn tí wọ́n ta sínú iràwọ̀ mi, kú, ní orúkọ Jésù.
14. Èmi yóò jẹ́ iràwọ̀ nínú ìran mi, ní orúkọ Jésù.